OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

ÌTÚPALẸ̀ ORÍKÌ ÀWỌN ÀṢÀYÀN TÌMÌ TI ÌLÚ ẸDẸ

(A CRITICAL ANALYSIS OF PRAISE POETRY OF SOME SELECTED TÌMÌ OF ẸDẸ)

OYÈRÌNDÉ, NASIRAT OYÈYẸMÍ

ARP13/14/H/0403

THESIS SUBMITTED TO THE POSTGRADUATE COLLEGE IN PARTIAL FULFILMENT OF THE REQUIREMENTS FOR THE DEGREE OF MASTER OF ARTS

ỌBAFEMI AWÓLÓWÒ UNIVERSITY,

ILÉ-IFẸ̀.

2016

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact **ir-help@oauife.edu.ng**

AUTHORISATION TO COPY

Title: Ìtúpalẹ̀ Oríkì Àwọn Àṣàyàn Tìmì ti Ìlú Ẹdẹ

(A Critical Analysis of Praise Poetry of some Selected Tìmì of Ẹdẹ)

Author: OYÈRÌNDÉ, Nasirat Oyèyẹmí

Department: Department of Linguistics and African Languages

Degree: M.A. (Yorùbá Language and Literature)

Year: 2016

I, OYÈRÌNDÉ, Nasirat Oyèyẹmí with registration number ARP13/14/H/0403, hereby authorise the management of Hezekiah Olúwasanmí Library to copy my thesis in whole or in part, in response to the request from individual researcher and organisations for the purpose of private study or research.

---------- ----------

Date **Signature**

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact **ir-help@oauife.edu.ng**

ỆRÍ ALÁBÒÓJÚTÓ

Mó jẹ́rìí sí i pé iṣẹ́ ìwádìí yìí jẹ́ ti OYÈRÌNDÉ Nasirat Oyèyẹmí (ARP13/14/H/0403), tó jẹ́ àkẹ́kọ̀ọ́ lábẹ́ àmójútó mi ní Ẹ̀ka-ẹ̀kọ Lìngúísítìkì àti Èdè ilẹ̀ Adúláwọ̀ ti Yunifásítì Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀, Ilé-Ifẹ̀.

---	---
Ọ̀mọ̀wé J.O. Sheba	**Déètì**
Alábòójútó	
---	---
Ọ̀mọ̀wé A.S. Sàlàwú	**Déètì**
Olórí Ẹ̀ka-Ẹ̀kọ́	

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

ÌDÚPẸ́

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ ọ̀gá mí ọ̀wọ́n tí wọ́n jẹ́ alábòójútó iṣẹ́ yìí Ọ̀mọ̀wé Láídé aya Sheba fún ìtọ́nisọ́nà, ìmọ̀ràn àti ìrànlọ́wọ́ tí wọ́n ṣe fún mi fún àṣeyege iṣẹ́ yìí. Ẹ ṣé o, olùrànlọ́wọ́ kò ní wọ́n yín o. Àṣẹ. Ọpẹ́ mi tún lọ sí ọ̀dọ̀ olórí ẹ̀ka ẹ̀kọ́ mi Ọ̀mọ̀wé Olúṣọlá Ajíbádé fún ọwọ́ ìfẹ́ tí wọ́n fi mú mi, fún àtìlẹ́yìn àti ìmọ̀ràn, mo mọ rírì yín Ọlọ́run aláàánú yóò san yín ní ẹ̀ṣan ohun rere yín. Àṣẹ.

Bákan náà mo tún dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn ọ̀gá mi wọ̀nyí fún ìmọ̀ràn òrèkóòrè tí wọ́n máa ń fún mi. Ọ̀jọ̀gbọ́n L.O. Adéwọlé, Ọ̀mọ̀wé Bídèmí Fábùnmi, Ọ̀mọ̀wé Ayọ̀ Ọ̀pẹ́fẹ̀yítìmí, Ọ̀mọ̀wé J.B. Agbájé, Ọ̀mọ̀wé J.A. Ògúnwálé, Ọ̀mọ̀wé Ṣẹ́gun Sàláwù, Ọ̀mọ̀wé Kọ́lá Adéníyì, Ọ̀mọ̀wé W.A. Jayéọlá, Ọlájùmọ̀kẹ́ Àjùwọ̀n, Ọ̀gbẹ́ni Bámgbádé àti Bùnmí aya Bernard. Ẹ ṣe mo dúpẹ́ o, mo gbà á láàdúrà pé Ọlọ́run a máa ṣe àtìlẹ́yìn fún un yín, àṣẹ.

Ọpẹ́ mi lọ sọ́dọ̀ ìyá mi ọ̀wọ́n Misirat aya Oyèrìndé fún ìnáwó àti àdúrótì wọn ní gbogbo ìgbà, ẹ ṣé o, ẹ ẹ́ pẹ́ fún mi o, àsírí yín kò ní tú, ẹ ò ní jẹ oúnjẹ ọmọ nínú ìbànújẹ́ o. Àṣẹ.

Mo dúpẹ́ gidigidi lọ́wọ́ ọmọ olóríire tí Olódùmarè fún mi: Imran Maryam Adéṣẹ̀wà fún ìfọ̀kànbalẹ̀ tí ó fún mi ní àsìkò iṣẹ́ yìí, Olódùmarè yóò dá ọ sí fún mi, n ó ṣe ìyá rẹ dalẹ́ o, Àṣẹ. Mo tún dúpẹ́ lọ́wọ́ ọkọ mi, adé orí mi Imran Mojeed Adékúnlé fún ipa tí wọn kó àti ìfaradà tí wọn ní ní àsìkò iṣẹ́ yìí. ẹ ṣe o, Olódùmarè kò ní paná ìfẹ́ wa o, à á pẹ́ fúnra wa o, a ò ní sú ara wa lágbára Olódùmarè, iwájú ní ọ̀pá ẹ̀bìtì ń ré sí, iwájú ní ẹ ẹ́ máa lọ o. Àṣẹ.

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn ọ̀rẹ́ àtàtà tí Olódùmarè fi rọ̀gbà yí mi ká, àwọn bí i Daniel Abíọ́dún, Adésọ́lá aya Ògìdán, Fèyíkẹ́mi Ọlárinre, Bilikis aya Shittu àti Olúwabùnmi aya Abíọ́lá fún àtìlẹ́yìn tí wọn ṣe fún mi, ibi gíga ní a ti máa bá a yín o. Àṣẹ.

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact ir-help@oauife.edu.ng

Ọpẹ́ mi lọ sọ́dọ̀ àwọn abẹ́nà-ìmọ̀ mí gbogbo fún ìtọ́sọ́nà ní gbogbo ìgbà. A máa rí yín bá o, ohun gbogbo tẹ́ ẹ bá dáwọ́ lé yóò yọrí sí rere o. Àṣẹ

Òǹtẹ̀wé mi ọ̀wọ́n Grace aya Adébáyọ̀ ẹ ṣe fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ yín, ẹ ó jèrè iṣẹ́ ọwọ́ yín o, orí olórí kò ní kérè iṣẹ́ tí ẹ ṣe. Àṣẹ .

Ní ìparí, mo dúpẹ́ púpọ̀ lọ́wọ́ àwọn olóore àti aláàánú mi gbogbo, Olódùmarè yóò fi rere san án fún un yín o. Àṣẹ

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact **ir-help@oauife.edu.ng**

Ìtọ́ka àkóónú

		Ojú ìwé
Àkọ́lé		i
Authorisation to copy		ii
Ìjẹ́rìísí iii		
Ìdúpẹ́		iv
Ìtọ́ka olóríjorí		vi
Abstract		ix
Àṣamọ̀ xi		
ORÍ KÌN-ÍN-NÍ: ÌFÁÀRÀ		
1.0	Ìfáàrà	1
1.1	Èròngbà iṣẹ́ yìí	3
1.2	Ibi tí agbára iṣẹ́ yìí mọ	4
1.3	Ìlànà ìṣèwádìí	4
1.4	Tíọ́rì àmúlò fún iṣẹ́ yìí	6
1.4.1	Tíọ́rì ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀	6
1.4.2	Ìwúlò tíọ́rì yìí	13
1.4.3	Tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀	13
1.4.4	Ìwúlò tíọ́rì yìí	18
1.5	Àfikún ìmọ̀	19

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

1.6

ORÍ KEJÌ: AÁYAN ỌMỌ̀RÀN LÓRÍ ÀYỆ̀WÒ ORÍKÌ YORÙBÁ

2.0 Ìfáàrà 20

2.1 Iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú lórí ohun tí oríkì jẹ́ 21

2.2 Iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú lórí ìpín-sí-ìsọ̀rí oríkì Yorùbá 25

2.3 Iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú lórí ìlò oríkì Yorùbá 27

2.4 Iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú lórí àkóónú oríkì 30

ORÍ KẸTA: ÌTÚPALẸ̀ ORÍKÌ ÀWỌN ÀṢÀYÀN TÌMÌ TI ÌLÚ ẸDẸ

3.0 Ìfáàrà 32

3.1 Ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ìlú Ẹdẹ 32

3.2 Ìtúpalẹ̀ àkóónú oríkì àwọn Tìmì ìlú Ẹdẹ tó jẹ láàrin 1817 títí di àkókò yìí 36

3.2.1 Tìmì Kúbọlájẹ́ Àgbọ́nrán (1817-1823) 36

3.2.2 Bamgbayé Ajẹniju (1823-1848) 43

3.2.3 Òjó Aróhánrán (1848-1856) 49

3.2.4 Ṣàngólámì Lágúnjú (1865-1884, 1891-1892 àti 1892-1893) 52

3.2.5 Lánṣebẹ́ẹ̀ Láṣebìkan(1892) 61

3.2.6 Gbédẹdélé Mọ́sùnlóyè (1893-1900) 64

3.2.7 Ayíloyè Oyèlẹ́kàn (1900-1924) 66

3.2.8 Ìpínoyè Abídogun (1929-1933) 68

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact ir-help@oauife.edu.ng

3.2.9 Sànúsì Àkàngbé (1834-1946) 74

3.2.10 John Adétóyèṣe Láoyè I (1946-1975) 77

3.2.11 Munirudeen Adésọlá Lawal (2008 di àkókò yìí) 85

3.3 Àfiwé àti ìgbéléwọ̀n ọba kọ̀ọ̀kan 88

3.4 Àgbálọgbábọ̀ 93

ORÍ KẸRIN: ÀGBÉYẸ̀WÒ ÌLÒ-ÈDÈ NÍNÚ ÀWỌN ORÍKÌ TÍ ÀGBÉYẸ̀WÒ

4.0 Ìfáàrà 95

4.1 Àwítúnwí 95

4.1.1 Àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ 97

4.1.2 Àwítúnwí àpólà 102

4.1.3 Àwítúnwí gbólóhùn 106

4.2 Àfiwé 109

4.2.1 Àfiwé tààrà 109

4.2.2 Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ 111

4.3 Àgbálọgbábọ̀ 114

ORÍ KARÙN-ÚN: ÀGBÁLỌGBÁBỌ̀

Àgbálọgbábọ̀ 115

Ìwé ìtọ́kasí 119

Abẹ́nà ìmọ̀ 122

Àsomọ́ 123

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

Abstract

The study collected and transcribed the oríkì of selected Tìmì of Ẹdẹ. Also, it identified and discussed the various thematic contents and the distinguishing features in the oríkì of the selected Tìmì. Further, it appraised the stylistic features of the poems. This was with a view to advancing the understanding of features that distinguish and connect different Tìmì of Ẹdẹ.

The study employed primary and secondary sources of data. The primary source included oral interviews with the incumbent Tìmì, selected chiefs, palace drummers, chanters and purposively selected traditional historians in Ẹdẹ. The secondary source included books, journal articles and the Internet. Data collected were transcribed and analysed using hermeneutical and sociological theories.

The study found that various thematic contents were represented in the oríkì of selected Tìmì. The thematic contents included the attributes of each of the selected kings, the place, space and power accorded to the kings among the people of Ẹdẹ and its environs. It also discovered that the oríkì of each Tìmì preserves the attributes of the selected Tìmì through time. It also showed that simile, metaphor and repetition were frequently used in the identified oríkì.

The study concluded that the contents and forms of the oríkì of selected kings are embodiments of history. The study further established that oríkì is a chronicle of interrelations of kings and their subjects in Ẹdẹ. The study also broadened the understanding of the perception of the kings by the Yorùbá, as contained in their oríkì.

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact **ir-help@oauife.edu.ng**

Àsamọ̀

Iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí ṣe àgbàjọ àti àdàkọ oríkì àwọn àṣàyàn Tìmì ìlú Ẹdẹ. Iṣẹ́ yìí tún ṣe àfàyọ àti ìjíròrò onírúurú kókó-ọ̀rọ̀ àti àwọn àbùdá ìyàtọ̀ tó jẹ yọ nínú oríkì àwọn àṣàyàn Tìmì. Ó sì ṣe àlàyé lórí àwọn ìlò-èdè tó jẹ yọ nínú ewì náà. Èròvgbà ìwádìí yìí ni láti ṣe àfikún sí ìlànà àgbọ́yé àwọn àbùdá ìṣe tó fi ìjọra àti ìyàtọ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn Tìmì Ìlú Ẹdẹ hàn.

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àmúlò ìlànà méjì láti gba ẹ̀rí jọ fún àpilẹ̀kọ yìí. Ìlànà àkọ́kọ́ ni ṣíṣe ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Tìmì tó wà lórí ìtẹ́ lákòókò iṣẹ́ ìwádìí yìí, àṣàyàn olóyè, `ayàn ààfin, apohùn àti àṣàyàn òpìtàn ibìlẹ̀ ní Ẹdẹ. Ìlànà kejì ni kíka ìwé, jọ́nà àti itàkùn ayélujára. Gbogbo ẹ̀rí tí a gbà jọ ni a dà kọ sílẹ̀ tí a sì ṣe ìtúpalẹ̀ wọn ní ìbámu pẹ̀lú tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ àti ìbára-ẹni-gbé-pọ̀.

Iṣẹ́ ìwádìí yìí rí i pé onírúurú kókó-ọ̀rọ̀ ló jẹ yọ nínú oríkì àwọn àṣàyàn Tìmì tí a yẹ̀wò. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ náà ni àwọn àbùdá Tìmì kọ̀ọ̀kan nínú àwọn tí a ṣà yàn: Ipò, àáyè àti agbára tí àwọn ènìyàn Ẹdẹ àti agbègbè rẹ̀ gbé wọ̀ wọ́n. Àpilẹ̀kọ yìí tún rí i pé oríkì Tìmì kọ̀ọ̀kan ń ṣe ìpamọ́ àbùdá àwọn Tìmì tí a ṣà yàn fún ìtúpalẹ̀ láti ìgbà-ìwáṣẹ̀ di àkókò yìí. Iṣẹ́ yìí tún fi hàn pé ìlò àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àfiwé tàárà àti àwítúnwí jẹ yọ lọ́pọ̀ ìgbà nínú àwọn oríkì tí a ṣe àmúlò.

Ní àkótán, iṣẹ́ àtúpalẹ̀ yìí ṣe àfihàn àkóónú àti ìrísí oríkì àwọn àṣàyàn ọba náà gẹ́gẹ́ bí àká ìtàn. Bákan náà ni ìwádìí yìí tẹ̀ síwájú pé oríkì jẹ́ àká ìtàn ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin ọba àti ìlú rẹ̀ ní Ẹdẹ. Iṣẹ́ náà wá jẹ́ kí ìmọ̀ àti ojú àmúwayé àwọn Yorùbá nípa àwọn ọba gbòòrò sí i gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú oríkì wọn.

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact **ir-help@oauife.edu.ng**

ORÍ KÍNNÍ

1.0 Ìfáàrà

Oríkì àwọn àṣàyàn Tìmì tí ìlú Ẹdẹ ni a ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí. Àwùjọ Yorùbá jẹ́ àwùjọ kan tó fún oríkì ní pàtàkì púpọ̀, wọ́n sì máa ń lò ó nígbà gbogbo yálà ní àsìkò ìdùnnú tàbí ìbànújẹ́. Kò fẹ́rẹ̀ sí ohun kan tí ẹ̀yà tí a ń pè ní Yorùbá yìí kò ní oríkì fún, yálà ohun abẹ́mí tàbí aláìlẹ́mìí. Bí ẹ̀yà yìí ṣe ni oríkì fún oyè ọba kọ̀ọ̀kan, bẹ́ẹ̀ náà ni ọba kọ̀ọ̀kan náà sì tún ní oríkì àdání tirẹ̀ èyí tó ń fi ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí irúfẹ́ ọba náà hàn, ní pàtàkì jù lọ bí àsìkò rẹ̀ ṣe rí nígbà tó wà lórí ìtẹ́. Ó máa ń fi ipa àti ipò wọn láàrin ìlú han, bẹ́ẹ̀ ló tún máa ń sọ púpọ̀ nípa ìhà tí ìlú kọ sí wọn. Gbogbo àwọn ohun tó jẹ́ àkóónú tí àwọn oríkì yìí kó rọra ni yóò jẹ́ àfojúsùn wa nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí.

Bákan náà, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọnà-èdè tó hàn de nínú àwọn oríkì tí a ṣà yàn wọ̀nyí, gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé èdè Yorùbá jẹ́ irúfẹ́ èdè kan tó rẹ̀wà púpọ̀. Nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí, àwọn Tìmì ìlú Ẹdẹ tí a ṣà yàn jẹ́ láàrin ọdún 1817 títí di àsìkò yìí; àwọn ọba tó ti jẹ́ ni:

1. Tìmì Kúbọlájẹ́ Àgbọ́nrán (1817-1823) – Agboolé Baba-ńlá Kúbọlájẹ́
2. Tìmì Bámgbáyé Ajẹ́nìjù (1823-1848) Agboolé Dóódù Fọ́lárìn
3. Tìmì Òjó Aróhánrán (1848-1856) – Agboolé Agúnyán-mọ́-seṣu
4. Tìmì Ṣàngólámì Lágúnjú (1865-1884, 1891-1892 àti 1892-1893) – Agboolé Dóódù
5. Tìmì Olúnlóyè (1884-1891) Agboolé Dóódù Fọ́lárìn
6. Tìmì Láńṣebẹ́ẹ̀ Láṣebìkan (1892) – Agboolé Baba-ńlá Kúbọláje
7. Tìmì Gbédẹdẹ́lé Mọ́sùnlóyè (1893-1900) – Agboolé Dóódù Fọ́lárìn
8. Tìmì Ayíloyè Oyèlẹ́kàn (1900-1924) – Agboolé Baba-ńlá Kúbọlájẹ́
9. Tìmì Ìpínoyè Abídogun (1924-1933) – Agboolé Agúnyán-mọ́-seṣu

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact ir-help@oauife.edu.ng

10. Tìmì Sànúsì Àkàngbé (1934-1946) – Agboolé Dóódù Fọlárìn

11. Tìmì Adétóyèṣe Láoyè (1946-1875) – Agboolé Láoyè

12. Tìmì Tìjání Ọládòkun Oyèwùsí (1976-2007) – Agboolé Baba-ńlá Kúbọlájẹ́

13. Tìmì Adéṣọlá Lawal (2008 di àkókò yìí) – Agboolé Pẹ́rẹ́

Nínú àṣàyàn wa yìí ni a ti mú ọba mẹ́ta ni agboolé Baba-ńlá Kúbọlájẹ́" tí orúkọ oyè wọn ń jẹ́ *Agbọ́nrán*; àwọn ni Tìmì Kúbọlájẹ́ Àgbọ́nrán (1817-1823), Tìmì Láńṣebẹẹ̀ Láṣebìkan (1892), Tìmì Ayíloyè Oyèlẹ́kàn (1900-1924). A mú ọba mẹ́ta ní agboolé "Dóódù Fọlárìn" tí orúkọ oyè wọn ń jẹ́ *Ajẹníjù*; àwọn ni Tìmì Bamgbayé Ajẹniju (1823-1848), Tìmì Sànúsì Àkàngbé (1934-1946). Tìmì Mọ́sùnlóyè (1893-1900). A tún rí ọ̀kọ̀ọ̀kan ni agboolé Dóódù Lágúnjú, Láoyè àti Pẹ́rẹ́, tí orúkọ oyè wọn ń jẹ́ Lágúnjú, Láoyè àti Láminísà, àwon ni Tìmì Ṣàngólámì lágúnjú (1865-1884, 1891-1892 àti 1892-1893) Tímì Adétóyèṣe Láoyè (1946-1975) àti Tìmì Adésọlá Lawal (2008 di àkókò yìí). Nígba tí a rí ọba méjì láti ilé Agúnyán-mọ́-ṣesu" tí orúkọ oyè wọn ń jẹ́ *Aróhánrán*; àwọn ni Tìmì Òjó Aróhánrán (1848-1856) àti Tìmì Ìpínoyè Abídogun (1924-1933).

Ìdí pàtàkì tí mo fi yan iṣẹ́ yìí láàyò ni pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ ti pọ̀ lórí oríkì Yorùbá yálà ti ìlú ni, ẹranko tàbí oríkì yòówù kó jẹ́, àwọn onímọ̀ kò kọbi-ara sí ìtúpalẹ̀ oríkì àwọn Tìmì ti ìlú Ẹdẹ, bí ó ti wu kó mọ. Gàgá yìí ni mo lérò láti di nípasẹ̀ yíyànnàná àwọn oríkì náà láti ṣe àfihàn àwọn àbùdá àdání àti àbùdá tí àwọn Tìmì yìí fi jọra wọn. Tí a sì ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọnà-èdè tó jẹ yọ nínú àwọn oríkì yìí pẹ̀lú.

Èrò wa ni pé iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò fi òye àti ìmọ̀ kún èyí tí a ti ní tẹ́lẹ̀ lórí oríkì àti lórí oríkì àwọn Tìmì ìlú Ẹdẹ. Bákan náà ni iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò jẹ́ ká mọ̀ pé onírúurú oríkì ni ó wà, bí ọba ṣe ní oríkì fún oyè tó jẹ, ló ní oríkì fún ìdílé ní agbo-ilé tó ti wá, ló tún ni oríkì ti ara rẹ̀ tó ń fi ìrísí, ìhùwàsí ati akíkanjú rẹ̀ hàn.

© Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria
For more information contact **ir-help@oauife.edu.ng**

1.1 Èròǹgbà iṣẹ́ yìí

Èròǹgbà iṣẹ́ yìí ni láti tan ìmọ́lẹ̀ sí oríkì àwọn àṣàyàn Tìmì ìlú Ẹdẹ nípa síṣẹ àkójọpọ̀ oríkì wọn. Ìwádìí yìí yóò tọpinpin bí àbùdá, ipa àti ipò àwọn ọba yìí ṣe ń jẹ yọ nínú oríkì wọn. Ìwádìí yìí yóò jẹ́ kí á mọ bí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ṣe jinlẹ̀ sí nípa àwọn ọba wọn. Nínú àpilẹ̀kọ yìí, náà ni a ti wo àwọn àbùdá tó fi ìyàtọ̀ ọba kan hàn sí òmíràn àti èyí tí wọ́n fi jọra, a sì wo àyípadà tó ti dé bá ìhun oríkì àwọn ọba tó ṣáájú sí tí àwọn òde-òní. Bákan náà, nínú àpilẹ̀kọ yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọnà-èdè tó jẹ yọ nínú àwọn oríkì náà.

For more information, please contact **ir-help@oauife.edu.ng**

OBAFEMI AWOLOWO UNIVERSITY